# IROHIN IMOLE

IM·L ·E A·E, TEN! GBOGBO LAWA
No. 730 SATURDAY, JUNE 27, 1964 (2D)


## Ijoba Se Isin Irantl Olubadan

IBADAN:- Olotu Iwọ Oru Naijiria, Oloye S. L. Akintọla sọ ninu ọrọ rẹ nibi isin iranti ologbe Olubadan ọba Isaac Babalọla Akinyẹle pe Ijọba I· inlẹ I· ọ Orun pa·o j·lo n·w· e·ia Ipiale na padanu nkan nla atip ni ihuwa si ni gẹgẹbi baba ·· ọrọ at·ye ti ọba na· ·ufun awọn enia.

Oloye S. L. Akintọla nsọ eyi nibi eyẹ isin iranti ti nwọn ṣe fun Ologbe Ọba na ·· ile Ọlọrun ni Arẹmọ, Ibadan Oloye Akintọla sọ pe enia ·la ni o ṣi yẹ ki awọn ṣe iranti Ologbe na.

Ninu ·rọ i·asu, Alufa Dokita J. Shoremẹkun sọ pe Ologbe Olubadan na jẹ enia pataki ati pe e·· rere ni ninu awọn ẹmọ ilẹ Naijiria, Alufa na tun sọ pe fun iduro awọn enia to wa sibi isin iranti na fihan pe Ọba Akinyẹle pe eni rere ni ati pe fun iru enia to jẹ larin awọn enia na.

Ni afikun Alufa Dokita Shoremẹkun sọ pe ni fẹran ologbe Ọba na ati pe ·ṣe ni Ọba Akinyẹle dabi David ninu iwe Bibeli eyi to jẹ pe ninu ipo Ọba ati ·ipa ọrọ esin Igbagbọ eyiti ọba na fi npa aṣẹ fun awọn enia ẹhin rẹ ati pe Ọba na ni ọkan igbagbọ lọkan pupọ ju.

Dokita Shoremẹkun to sọ siwaju si i Ologbe Olubadan yio jẹ arikogbọn ati fu· iranti fun awọn Ọ· ọlọpọ e·ia

WO OJU EWE KẸFA

### "Abẹrẹ Bọ Lọwọ Adẹtẹ O Dete, Ọrọ Ba Lẹ O D'ero"

# EJỌ OLOYE AWOLỌWỌ HA DI ỌSẸ TI MBỌ BI ?

EKO:- Ni deede agogo mẹjọ owurọ ana ni gbogbo ori ọdan ti iṣe iwaju Ile ẹjọ gigajulọ fun orilẹ ede Naijiria ti kunṣọṣọ fun wọn onimọto, onikẹkẹ ati awọn ẹlẹsẹ ti gbogbo wọn damuso ti nwọn nreti abọde Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre ati awọn enia mejila mirau pẹlu rẹ ti Ijọba mba ṣejọ id·te ati ifi ·p· ko awọn ohun ọṣẹ wọlu lọna aito



Irohin fi ye wa pe, gbogbo awọn enia na sọ pe, ni ọjọ Ẹti t· ise ọjọ kẹrindinlọgbọn oṣu yi ni awọn gbọ wipe, nwọn o ṣe ẹjọ Oloye na

Gẹgẹbi eto, mọto ti yio ko awọn olujẹjọ na wa si Ile ẹjọ gbọdọ de sinu ọgba kotu ni deede agogo mẹjọ abọ ki awọn adajọ si bẹrẹ ẹjọ wọn ni deede agogo mesan owurọ.

Ṣugbọn nigbati gbogbo awọn enia na duro titi di agogo mewa ti nwọn ko si ri awọn ọlọpa ti mọto ko si tu· ·e ·····olujẹjọ



Lateef Jakande

ni awọn adajọ yio ṣe ẹjọ oloye na, ṣugbọn eko tun gbọ ohun ọjọ bẹ mọ ti ilẹ ana fi ṣu.

Ni ijẹt· ti iṣe ọjọ kẹ dọgbọn oṣu yi ni a gbọ wipe awọn adajọ mararun ṣe ipade bonkẹlẹ kan ninu ile ejọ na. a si lero pe ohunti nwọn ṣe ipade na le lori ni lori idajọ ẹjọ Oloye Awolọwọ.

Nigbati nwọn pari ipade wọn, onirohin wa fi ye wa pe ni ọjọ keji oṣu ti mbọ yi ni ile ẹjọ na yio mu ipade ijoko wọn wa sopin ti Ọlọla Adetokunbọ Ademọla yio gba isimi ati awọn adajọ miran pẹlu rẹ·

Otun ṣe alaye pe boya ni ọjọ ti awọn adajọ na yio gba isimi ni nwọn fẹ ṣe ẹjọ na. Ti nwọn ba si ti ṣe idajọ tan, ki gbogbo wọn o gba isimi wọn ki nwọn si lọ si idalẹ.

Onirohin wa na fi



Ọgbẹni Ọdẹsanya

ye wa pe. awọn adajọ na ko fẹ duro nile (Eko) lẹhinti nwọn ba ti ṣe idajọ Oloye na tan.

A tun gbọ wipe lati opin ọṣẹ to kọja yi ni Ọlọla Louis Mbanefo adajọ Agba fun Ipinlẹ Ila-Orun Naijiria ti de si Eko, atipe nitori ọrọ ẹjọ Oloye Awolọwọ yi ni adajọ na se wa si Eko, o si di igbati nwọn ba ṣe idajọ Oloye na ki Ọlọla Mbanefo to pada si Ipinlẹ Ila Orun Naijiria.

WO OJU EWE KẸFA

### Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ

na de, ni gbogbo awọn enia na ba nba ẹsọ wọn sọrọ, ti wọn si nlọ si ile ni ọkọọkan, eji eji titi gbogbo wọn fi tuka yanga ni nkan baagogo mọkanla.

Ọkan ninu awọn enia na sọ fun oniwe irohin wa pe, "Ọga ni ọjọ wo ni e gbọ pe, nwọn fẹ ṣe ẹjọ Oloye Awolọwọ?"

Oniwe irohin wa dahun pe, "Emi n· wa bere lọdọ awọn alaṣẹ Ile ẹjọ ni, nko si ti ri wọn, ṣugbọn ohunti nwọn ba wi ti mo ba ri wọn o m· · gbọ ninu iwe Irohin ni ọla"

Lẹhinr·a ni Okunrin na wa nda sọrọ lọ pe, "Bi o ba pẹ titi, Alamisi a kọla, ni Ọjọ kan sa ni eo ṣe ẹjọ na, ṣugbọn lati Ọsẹ ti no bọ si yi, nko ni ṣe iṣẹ kan, oju mi ni nwọn o ṣe ṣe ẹjọ na ko ni ṣẹhin mi."

Gẹgẹbi irohin ti·a·ti ngbọ ni wipe, ni ana



Omiṣade

# IWA AIKO NI ITIJU LARIN AWA ENIA ATI ẸRANKO

**Lati Ọwọ S O Jaiye Eko**

Nigba kan gbogbo awọn ẹranko pade ninu afin igbo wọn. Nigbati nwọn pade tan ni ọkan ninu gbogbo wọn bẹ soke o sufe wipe o yẹ ki gbogbo wọn bi ẹnikọkan wa ma sọ alebu iyawo wọn. Ati pe nwọn fẹ mọ ohun to buru ju lọ ninu iwa obinrin.

Lẹsẹ kanna ni agbọnrin tabi igala bẹ soke o sọ pe aya on le jẹ ila onila ju ninu oko oloko ati pe iru iwa ole bayi ko dara rara.

Ikun to jẹ ọkan ninu awọn ẹranko to kere fo soke o wipe aya on fẹran ati ma bọ sile bọ sode ni ala oko ati oloko; nitorina fun idi eyi oni on ko fẹ iru iwa buburu bayi ati pe itiju ni fun obinrin to nkiri ti ki gbe ile rẹ.

Ẹfọn dahun pe aya ti on fẹran ati ma tẹle on kiri ninu papa, nitori nipa titẹle on ni ọwọ ọdẹ ma to on fun idi eyi iwa to buru ni ki a ma a tẹ le ọkunrin kiri ninu igbo.

Bi oti dakẹ ni Ọbọ dahun wipe aya on fẹ fẹran ati ma bẹ kiri ni ori igi pẹlu ọmọ lẹhin, Eyi papa jẹ ohun ẹdun fun on wipe ki aya on ma ji igbado onigbado ya kiri ninu oko.

Iwa ole ati alebu ni eyi fun on pe iyawo on njale ninu oko oloko. Bi Ọbọ ti dakẹ ọrọ lori alebu aya tirẹ ni Ologbo dahun pe aiya ti on ki jẹ ki awọn ekute ile ṣereni ode bi nwọn ti nlẹ. Ati pe o gbadun ati ma a kẹ imẹọ-mẹọ kiri ile. O wipe itiju lojẹ ki iyawo on ma a dọkun ati ma ke kiri iyara oniyaro.

Bi ologbo ti dakẹ lati sọ ọrọ ẹgan ti iyawo rẹ ni Ekute yọ jade pẹlo iwariri pẹlu iterubọjo nitori o ro wipe ologbo wa nitori on. Ekute bọ siwaju kubẹkubẹ niwaju awọn ẹranko pe aya on ko ṣe sọ nitori ajẹni lẹ ni aiya on jẹ.

Ati pe o fẹran ati ma ṣe a fọrọra onjẹ olonjẹ ni ile, o tun bere lọwọ awọn ẹranko pe ewo ni ki aya ile ma jẹ ki ẹlẹran tabi ẹlẹja ma fi nkan wọn pamọ O ni iwa yi lo buru julọ ninu obinrin ile.

Bi ekute ti pari ọrọ tirẹ ni Adiẹ dahun wipe ẹku ikalẹ o ẹnyin ẹranko nla ati kekere. O ni bi otilẹ jẹ pe ẹ ko pe on si ọrọ nyin ṣugbọn on ni gbolohun kan sọ si ọrọ na.

O ni ohun to buru julọ ninu ọrọ iwa aya ti on ni pe ko dara to fun aya ẹni ki o fi ekanna tan ilẹ tabi igbẹ ẹnigbẹ ati pe ko dara ki onikẹlẹbẹ ma tu kẹlẹbẹ silẹ aya ẹni tun ma fi agogo ẹnu tan jẹ kiri ile.

O tun dahun si pe o jẹ ohun itiju ki aya ẹni ma fi agogo ṣa gbogbo kokoro jẹ kiri aiye rẹ Awọn ẹranko wipe o ku tọ ọ. Iwa yi kodara to eyi ko dara to rara.

Ninu awọn ẹranko to joko ni Ẹlẹdẹ ni bi to joko ti o ke hu u hu nwọn bi lere wipe baba odo o wa sọ tirẹ fun wa gbọ o.

Baba odo o wa dahun pe ko si bi o ti ri. Nitotọ ni gbogbo nyin nsọrọ ti on gbọ ọrọ nyin. Ṣugbọn



Ọgeni S O Jaiye

ẹnyin paapa mọ iwa obinrin on ju on papa lọ. Ẹ wo ni ohun itiju to buru ju pe ki a wo aṣọ dada fun aya ẹni ki o wa jẹ wipe inu rẹ lo ma yi wọ lọ lati lọ pafọ.

Oni wo iyawo on ti sanra to yi ti ori rọpọtọ ti ọra fẹrẹ di ni imu ati papa o sọrọ fun lati jẹ onjẹ ajeju ṣugbọn iwa itiju ni ki a ma le mu aya ẹni lọ si ode nitori iwa eri ati iṣogo ninu gbogbo ijẹkujẹ.

O dahun pe ẹ gba eyi pe iwa igbadun eri ni o buru julọ ninu obinrin.

Bakanna Aja dahun wipe iyawo ti on le kiri ita a si ma jẹ igbẹ, kekere ni eyi o ni aya on fẹran ati ma dọkọ larin ita gbangba ati pe iwa ikọkọ ita gbangba nigaiya ti on ma nṣe e.

O ni aya on ko ni lari ka mọ aiṭọ. Bi oti pari ọrọ tirẹ tan ni Ijapa bọ sode ninu irawe Igbo jẹjẹ.

Oni kabiyesi Kiniun ọba awa ẹranko o ni toto mo juba gbogbo ẹnyin alagbara igbo ati ẹnyin ti ko lagbara to wa larin ọmọ enia

Oni on gba gbogbo alebu ti nyin ti nsọ lati ọjọ melo yi wa oni on tọrọ gafara nyin lati sọ ti on fun nyin Oni yanibo iyawo ti on dara pupọ Ṣugbọn ko mọ itiju rara

Nitori na iwa itiju lo buru julọ ninu obirin ati pe ko si ẹniti o mọ itiju to jẹ fjaiẹ kanna ko si ẹniti o mọ itiju Iwa eri kan

Bayi ni gbogbo ẹranko gba wipe aini itiju lo buru julọ. Aini itiju jẹ iwa to ba diye jẹ lode oni Aini itiju ti a mọ ẹtọ tabi ohun ti o dara lati ṣe Nitori na ohun ti jẹ aiye ni gbese Ioni ni aini Itiju

Li ode oni a wipe ọpọ ninu awọn ti a ro wipe oyẹ ki nwọn mọ ohun ti o tọ ko mọ rara Ọpọ awọn miran ni ofi aini bọ sinu idanwo gbogbo ohun pupọ ti ẹlomiran nfi ṣe ayọ ni o jẹ ohun ti ẹlomiran nfi aṣọ bori wọn lati ri pe o jẹ iwa eri.

Ko si ohun alebu ti aini itiju ko le mu ba ọmọ enia Ko sl ẹniti o mẹ itiju ti ojẹ fi aye silẹ fun Iwa ibajẹ ki ibajẹ

Ọpọ ile ni o ti bajẹ nitori aimọ itiju bakanna ni ọpọ obirin lo nparọ ọkọ bi ẹni parọ aṣọ ati igele lojojojumọ

Nitori na o ye ki gbogbo ẹniti owa ninu aiye kọ lati ni iwa itiju Oye ki a ma tẹ le iwa mimọ ni gbogbo aiye wa.

## Awọn Ọmọ Oke - Ọdẹ L'Eko Se Ajọdun

EKO:- Irohin ko to afẹjuba ni ajọdun ti ẹgbẹ Obirin ọmọ Oke Ọdẹ ṣe ni ọjọ aiku ti se ọjọ kẹrinla osu kẹfa Ọdun yi ladugbo loita l'Eko ẹsẹ gbogbo ọmọ ẹgbẹ lope ṣọṣọ lọjọ na

Iya ẹgbọ iya-Afin Wuraọla ti ise iya Rabiatu ati awọn isorọ'e re awọn bi ati iya Gani Gbegbo iyawo Alhaji Glori i iya Kadiratu ati iyawo Alhaji Jeje Ayoka iyawo Alhaji Kari mu eti gbogbo awọn yoku ṣe bẹbẹ lọjọ na nwọn si na wabiwọsi owo

Nwọn si ṣe eto atata nipa bi awọn Oke-Ọde yio ma ni ilọsi-aju ni igba gbogbo

Nwọn si ṣe Akanse isin fun ẹgbẹ wọn ati Ilu wọn ajeti ni wọn fi orisirisi onjẹ adidun ọjọ na ṣe.

E Ma a Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojoojumọ Ki ẹ Si ma Polowo Ọja Nyin Sinu Rẹ Pẹlu

OKUSANYA SỌ PE;

# Ẹ Kọ Ẹgbẹ Dẹmọ Silẹ

IMODI-IMOSAN:—

Awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre to wa ni Imọsan ati Imodi Ijẹbu ṣe ipade nla kan ni ọjọ Abameta ni ilu Imosan wọn euis pọ lọ bi omi, to jẹ wipe aiye ko gba rara, awọn ti o aduro pọju awọn to joko lọ. Nigbati aye ko si mọ, ọpọlọpọ ni awọn ti o nyọju loju ferese, nigbati oju ferese tun kun fun enia ni awọn e n i a ba wa, toko nita ti nwọn sj wa gbe ẹrọ gbohungbohun sita iji awọn to wa ita nsi ngbọ ọrọ ti nwọn nsọ ninu ile

Oloye E. Okusanya sọ fun awọn enia ti o le ni ẹgba (2,000) pe ki gbogbo wọn duro ti ẹgbẹ ọlọpẹ gbọin gbọin ati asiwaju ẹgbẹw a na, Oloye Ọbafẹmi Awolowọ, o so wipe, idi ti o fi y ẹ ki nwọn rọgba yi ẹgbẹ na ka ni awọn idi pataki wọnyi;

Nitoripe nigbati ẹ g b ẹ ọlọpẹ si n ṣ e Ijọba nwọn pese iṣẹ f u n wa gbogbo oju oju ọna ni nwọn tunṣe daada, ẹkọ ọfẹ, oogun ọfẹ fun awọn ọmọ - owọ titi de ọmọ ọdun mejidi nlogun eti alafia ilu.

O wa bere pe, kini Ijọba ẹgbẹ Dẹmọ ṣ e f u n awọn ọmọ ilu Imodi ati Imọsan? Gbogbo awọn e n i a n a dahun pe, n w ọ n ko ṣ e nkankan. Ni ariwo Awo! Awo!! Awo!!! ba gba gbogbo adugbo na kan. Oloye Okusanya wa sọ pe, nigbati Ijẹba Dẹmọ ko ṣe wa ni anfani kan ko yẹ ki a ṣ ẹgbẹ wọn O wa kilọ f u n gbogbo enia pe, ki nwọn sọra, ki nwọn ma gba ẹtan jẹ ẹgbẹ Dẹmọ rara,

Ẹkọ wọn pẹlu owo osu wọn, Ni gbogbo awọn enia imosan ba fo hun sọkan Ipe awọn ni igbẹkẹle laga wọn Oloye E. Okusanya, awọn yio si ṣe olotitọ si ẹgbẹ Afẹnifẹra ti o bẹru Ọlọrun.

Nwọn gbadura ki Ọlọrun tete da alafia pada si ipinlẹ Iwọ Orun, Nwọn Lan sara si Oloye E. Okusanya fun di duro tio duro ti ẹgbẹ Afẹnifẹre ni idunta nigbti edeaiyede bẹsilẹ larin ẹgbẹ na. Nwọn tun sọ pe, awọn ko ni igbẹkẹle si Oloye Akintọla ati igbakeji rẹ Oloye Fani-kay de.

Ki ipade na to tuka nwọn ni awọn ni igbẹkẹle si Oloye Obafẹmi Awolọwọ ati ẹniti ndele de, Alhaji D. S Adegbenro.

## Imọran Fun Awọn Ọmọ Ile-Iwe

Lati ọwọ BỌSẸDE SHOYINKA
Ansar—Ud—Deen School Itirẹ

Ẹ ku owurọ o
Ẹnyin ọmọ ile iwe
Ẹlẹgbẹ mi
Ojo de, otutu
Si de bakanna
Ẹ ma a wọ
Aṣọ ti o nipọn
Ẹ maṣe fi
Aiya nyin silẹ
Ọpọlọpọ ni ko bikita
Nipa fifi ẹse
Wo omi ọgbara
Ẹnikẹni ti o ba
Nṣe eyi ninu yin
Ki o dẹkun
Lati maa ṣe bẹ ẹ
Kanyun ni o
Nko ba enia
Ọpọlọpọ kundun
Gari mimu
Laseko ojo
Eyi ko dara rara
Otutu ti o le
Fa aisan buruku
Ni i ko ba enia

Nitori idi eyi
Ẹnyin ọmọ ile iwe
Ẹlẹgbẹ mi
Ki i ṣe dandan
Lati mu "tea"
Tabi "Ovaltine"
Ẹle fi ẹkọ gbigbona
Dipo nkan wọnyi.
Ẹ maa wọ
Ẹwu ojo yin
Lo si ile iwe
Lasiko ojo
Toripe t'ojo
Ba pa enia
Ni apaju
Otutu ti o le
Mu arun silẹ
Lara enia
Ni i mu wa.

Odigbakanna o, ẹnyin onkawẹ mi ngo ma a sọ itan kan fun yin ni ọjọ miran ti akọle rẹ nje

"IMỌTOTO DARA"


# MODUPE PRINTING PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING
*Many Firms Patronise* M O D U P E P R E S S
*Because Of Their:—*
MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHODS
PRINTING

*For Your Next Printing Jobs:—*
Just Call 21985 – Leave the rest to Modupe
We Guarantee Neat Work And Quick Service

**Modupẹ Printing Press**
**16, Bamgbose Street**
Phone21985, Lagos.



AWỌN EGBOGI ATAMATASE PATAKI TI O WA LATI ILU JAMANI FUN ITỌJU ARUN ARA ATI OJU-DIDUN PẸLU EKINI:-

## SEDO – PAYAL



(IPARA BI ORI)

Jẹ ojulowo egbogi lati fi ṣe iosan orisirisi arun awọn ARA" gbogbo ti o ba mba enia ja lara tabi o de ara ẹbi ọwọ ẹsẹ tabi ara hihun tabi didun nigbakugba narun tabi akọ Inarun, Ewo, Rorẹ kakiri oju, Ela lapa ẹpa Ara sisu Alefọ Ekusa lori ọmọde tabi agbalagba egbo ẹsẹ tabi Adaajina egbo ẹsẹ ati orisirisi awọn amodi tabi awọn arun ara omiran gbogbo.

BẸNA SI EGBOGI.

Dara pupọ julọ fun awọn ti amodi ti a darukọ wọn si oke iwe yi ba nyọ lẹnu nitoripe iṣẹ rẹ ni lati ma mu gbogbo awọn "kokoro" buruku gbogbo ti o ba wa ninu "ẸJẸ ARA" enia, san patapata a si ma a iṣẹ ribiribi ninu "oju" enia pẹlu. Awọn ti oju wọn a ma "nsu" tabi wo baibai tabi ti wọn ko le riran daradara lati ọna jinijini tabi ti o bdal ẹnipe nkankan wa afara si oju wọn yio bẹrẹ si riran Kedere.

Bi o ba ti le gbiyanju lati ma lo egbogi Jamani yi dede fun igba diẹ alafia yio de si ọ ju gbogbo rẹ lọ egbogi Furunculosin yi a tun ma mu igbọuṣẹ wọrọ wọrọ wa fun awọn ti inu wọn bale tabi ti wọn ki rigbonṣẹ dede lojojumọ tabi ti igbọnṣẹ wọn mn nle kokoro nipa bayi jẹdijẹdi a bẹrẹ si ma yọ wọn lẹnu bẹni o si dara fun lilo fun awọn onijẹdijẹdi pẹlu awọn egbogi meji yi yatọ si gbogbo awọn ọbirọbi ti wọn nta kakiri Ṣọbu ilu Eko ati igberikọ Bere wọn ni Ṣọbu awọn:-

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, Tinubu Square Lagos

# IROHIN IMOLE

IMOLẸ ORB AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No, 730 SATURDAY, JUNE 27, 1964 (2D)


## "Ko Si Ija Ninu Egbẹ Alakukọ"

EkO:— Ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ ketalelogun oṣu yi ni awọn ọmọ Alakuko N C N C sọ ni Eko pe ko si ija kankan larin awọn ọmọ egbẹ wọn egbe na tun ṣe ikilọ fun awọn ọm egbẹ oṣelu kan ti nwọn fẹ mu da yọ eyi to fa ija wa si arin awọn egbẹ na ati pe ko si ohun to le da iru nkan bẹ si arin egbẹ wọn

"EṢẸ"

Awọn ọmọ ẹgbẹ na sọ ninu oro wọn pe ninu awọn ọmọ na gbiyanju lati ma da ija silẹ larin ọmọ egbẹ Alakukọ nipa fifi awọn oniṣẹ mẹfa lati ba wọn ma tẹ ade bi awọn o ti ma gbogun ti awọn Olori ẹgbẹ Alakukọ.

Awọn ọmọ egbẹ na tun sọ pe awọn si fẹ ki iru awọn enia bẹ mọ pe iru iwa bẹ jẹ ẹṣẹ ninu iwe ofin ẹgbẹ wọn ati pe fun ninu awọn ọmọ egbẹ na lati fa oju awọn oniwe irohin mọra lati le fi ma da rogbodiyan silẹ larin ọmọ egbẹ wọn.

Awọn ọmọ egbẹ na tun sọ pe iru iwa bayi si jẹ nodi si ofin egbẹ ati pe iru awọn iwa bẹ si pelu awọn nkan miran to pe awọn ọmọ ẹgbẹ na yio jiroro le ninu ijade ẹgbẹ a ti nwọn yio ṣe laipẹ yi.

# Obinrin Kan Gba Ọkọ Mọ Ọrẹ Rẹ Lọwọ !

EKỌ:— Kẹkẹ pa mọ gbogbo enia lẹnu nigbati Iyawo ile kan Iya-afin Rachael Adeniyi Ajala nsọ niwaju adajọ ile ẹjọ kekere Eko ni Ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kẹrindin logbon Oṣu yi pe, Ọrẹ korikosu on Omidan Henriett gba Ọkọ mọ on lọwọ ninu Ọdun ti awa ninu rẹ yi.

Iya afin Rachael Ajala ṣe alaye fun ile ẹjọ, pe, nigbati ti Olorun fi Ọmọ kunrin kulumba kan tan on ati ọkọ on lọrẹ, ni awọn ba fi ime ipe ranṣẹ si gbogbo enia lati wa ba awọn yọ ayọ nigbati o di ọjọ kẹjọ ti awọn bi Ọmọ na on si tun jẹ diẹ ninu awọn to jẹ ore atata ati korikosu.

Nigbati awọn ọrẹ on de gbogbo wọn joko si oju kan ṣoṣọ lẹhin ti gbogbo wọn jẹ ti nwọn si mu tan ilu nrinlẹ gbingbin gbogbo wọn si bọ si agbo nwọn njo ni meji, mẹta.

Nibiti awọn enia na ti njo ri on ba pe ọrẹ on ninu agbo-ijo on si mu lọ ki ọkọ on oko mi gba ọwọ lọwọ re on na si gba ọwọ lọwọ ọkọ ni awọn mejeji rẹrin si ara wọn on si sọ fun ọkọ on pe ọkan ninu ọrẹ korikoṣun on l'Eko ni yi.

Sugbọn lẹhinti awọn ti se ikomọ jade tan ni ọrẹ on Henrietta wa bẹrẹsi para ile on ju bo ti yẹ lọ on ṣe bi o wa nwo ọmọ on, aṣe ọkọ on lo nwa o ko pẹ pupọ lẹhin eyi ni iṣẹ gbe ọkọ kuro l'Eko lọ si Ibadan on si duro l'Eko pe ti ọmọ on ba dagba on yio si lọ ba ọkọ on.

Ko pẹ pupọ ti ọkọ on lọ si Ibadan ni on ba lọ ṣe ibẹwo rẹ nigbati on de ọdọ ọkọ on ni Ibadan ni on ba ọrẹ on Henrietta lo ba "tapanpa" sori bẹdi (bed) ọkọ on bi o ti ri on lo sare dide ẹru ba ko si mọ ohun to on le sọ.

Nigbati on fẹ ma baa ja lo ba sọ fun on pe ọrọ na ko pariwo bonkẹlẹ ni ko jẹ ki ajiijọ ṣe kini na nitoripe oyun to wa ni iku on yi ọkọ on (Ajala) lori oyun na eyi lo si fa ti on wa ba ni Ibadan pe ti ko ba fẹ on ki o gba oyun inu on ṣugbọn nibi ti awọn ti nsọrọ yi lọwọ ni ija ba de awọn ṣi bẹrẹ si bu ara wọn jẹ bi aja ti ebi npa nigbati ọkọ awọn ba de ko ba gbe awọn lọ si ile iwosan.

Siwaju eyi ni Ọga Ọlọpa to ba ọdaran na ṣẹjọ, Ọgbẹni C. B. Amalu sọ fun ile ẹjọ pe Rachael Adeniyi Ajala on ni Iyawo ti ogbni ni Ajala fẹ ni kotu osi o fun loruka awọn mejeji si gba lati fẹ ara won ki wọn si jijọ ma gbe pọ ni jọ niri jẹ ati ijọ airijẹ.

O tun sọ siwaju pẹlu pe, Rachael ti nsọ fun Henrietta pe ki o ma ṣe wale ọkọ on mọ nigbati o si ba ni ọdọ ọkọ rẹ ni Ibadan ni ọjọ na ni o ba sọ fun Henrietta pe. "Loni li osinmi si wa sile ọkọ mi, mo mu ọ loni ẹjọ gbogbo ni to'le ọjọ kan ni ti olo on" ni awọn mejeji ba wọ gidigbo.

Nigbati Ọgbẹni Adeniyi Ajala de lati ibi iṣẹ lo si ba awọn mejeji ti awọn ti ke ara wọn jẹ bi aja o si gbe awọn mejeji lọ si ile iwosan fun itọju lẹhin ati awọn mejeji ti gbadun tan Rachael ba pe ọrẹ l'ẹjọ pe o ji on l'ọkọ g e.

Lehinti adajọ agba Iya afin Okunuga sọ pe nitoripe Henrietta jẹ olowo tabi onisowo atata ko sọ wipe ko gba ọkọ ọlọkọ ṣugbọn o yẹ ọjọ na si ọjọ Abameti iṣe ọjọ kọkanla oṣu ti nbọ yi.

## Ejọ Oloye Awolọwọ Ha Di Ọsẹ Ti Mbọ Bi ?

Lati Oju Ewe Kini

Onirohin wa kan tun tawalolobo pe, ninu ọsẹ ti ao bọsi yi ni nwọn o ṣe ẹjọ Oloye Awolowọ; Ṣgbọn a ko ti ri ohunkohun gbọ nipa ọjọ ti awọn o ṣe ẹjọ na

Bi a ba ti tun gbọ ọrọ na si ẹo tun maa gbọ ninu iwe Irohin wa.


LATI OJU EWE KINI


ati pe enia ko gbọdọ wa fun akara ni kan ṣugbọn ki o jẹ ki ọrọ Ọlọrun ma wa ninu igbesi aiye on.

Alufa na tun sọ pe ti awọn enia ba nṣe bẹ pe on lole mu ki alafia ati pe on na lo si mu ki igbesi aiye Ologbe Ọba na dara bayi papa pe, yio jẹki alafia wa ninu ilọsiwaju orilẹ ede.

Dokita Shotenieken nọ gbogbo awọn ijọ pe ilu kan ti wa to jẹ pe nwọn sọ gbogbo ilu na di ilu igbagbọ ati pe on ko ri idi ti awa enia ile Naijiria ko le sọ ilẹ wa di bẹ ati pe o si ti wẹ ninu ofin ilẹ wa lasiko Ominira pe awa enia ile na ni aye lati sin Ọlọrun gegebi o ti wu wa.

## Egbẹ Ọmọ Ibilẹ Takete

Afi Iwe yi pe gbogbo awọn Ọmọ Ibilẹ Takete ati gbogbo Agbegbe rẹ lọkunrin ati lobinrin ti wọn ngbe ni Ilu Eko ati Agbegbe rẹ si ibi ipade pataki ti ao se ni ọjọ kejidinlogbọn (28:6:64) oṣu ti awa ninu re yi ni No, 1, Coates Street Ebute Mẹtta ni agogo meji ọsan. Pataki ọrọ ti ao sọ ni pa rẹ ni ilọsiwaju gbogbo ọmọ Ibile Takete ti o wa ni Ilu Eko,

LATIFU ADEYERI
AG Chairman


## AKIYESI PATAKI

Ẹnikeni ti o ba fe lati ra iwe Irohin Imọlẹ" ni Ibadan ati agbegbe rẹ yio ri ra lọdọ Asoju wa, Ọgbẹni Lateef Animashaun, 1 Araromi Street, Ibadan

Kọbọ meji (2d) pere ni a nta a.

OLOTU



Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgbohe Street Lagos Phone 21985
Editor:- TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street Lagos 27/6/64